# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## MO NRETI ALFA BOLAJI AKEWUKEWE

Inu mi dun nigbati mo gbọ pe Alfa S. B. Bọlaji Akewukewe yio wa si ọdọ mi lati ṣe alaye ẹsin fun ara wa lati igbana ni mo si ti nṣe ireti rẹ.

Mo fẹ ki o tonu jinlẹ dada ki o to wa, nitoripe ko si aye a ti maa ko si iyara lati sọ ọrọ Ọlọrun gẹgẹ bi iru aṣa ti o da ni Ogbomọshọ pe ẹnikẹni ti o ba fẹ gbọ alaye on pẹlu Evangelist Akande ki o maa sanwo ki nwọn to wọle, ko si aye iru rẹ nihin rara. Ni gbangba loju t'awo t'ọgbẹri ni ao gbe duro se alaye fun ara wa.

Mo si fẹ ki o tun Alkurani rẹ kọ daadaa nitoripe lati sura 1 de 114 ni ao fi ṣe alaye.

Ekeji :— Nipa ti ọrọ Bibeli ti o si sọ pe o tako ara wọn ọrọ na ko ri bẹ ẹ rara mo si ti mura silẹ lati ja irọ rẹ.

Ẹkẹta :— Ti ko ba gba pe Alkurani nja ara wọn ni iyan ki o maa bọ man laa ye e,

Ẹkẹrin :— Jesu Kristi ni ọmọ Ọlọrun on si ni Olugbala gbogbo awọn ti o ba gba a gbọ.

Ẹkarun :— Alaye nipa Ọlọrun Mẹtalọkan, Ọlọrun-Baba, Ọlọrun-Ọmọ ati Ọlọrun-Ẹmi-Mimọ.

Gbogbo ibiti Alfa Bọlaji juwe ninu bibeli ko ri bẹ ẹ rara, ki oma ṣe ro pe nitori ti on ti wa ni Eko o ti ni imọ pari, Ti o ba si mbọ wa ki o jẹki ngbọ ọjọ na gan ti yo de ọdọ mi ninu Iwe Irohin Yoruba. Ti mo ba lọ si idalẹ ma tete pada wa pade rẹ. Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
Joel Adewọye
c/o Post Master,
ILOBU,
via OSHOGBO.

## G. O. ỌKẸ GBA IYIN

Inu mi dun pupọ fun alaye ti Ọgbẹni G. O. Ọkẹ, Jos, ṣe lori "Onigbagbọ Ẹ maa yọ" eyiti o jade ninu iwe Irohin Yoruba ti 24/9/51. Mo dupẹ lọwọ Ọgbẹni yi fun alaye rẹ na.

Alaye rẹ fi idaniloju han gbogbo enia pe ẹnikẹni ti o ba gba Jesu Kristi gbọ pe Olugbala ni ni yio ni ipin ninu iye-ainipẹkun pataki julọ nipa Alkurani ti o tun tọka si pe o jẹri gbe wa.

Mo si tun ki Evangelist Akande Ogbomọshọ, Idowu Ajibnrere ati Alice Jokotade, Eko, fun alaye wọn lati maa kede Igbala fun gbogbo araiye.

Mo si fẹ ra Alkurani ni ede Yoruba ẹnikẹni ninu awọn onkawe Irohin Yoruba ti o ba ni fun tita tabi ti o ba mọ ibiti mo le ri i ra ki o jẹki ngbọ o.

Emi ni
M. A. Ogunrinde
KATCHA


KO SI OTUTU MỌ



MENTHOLATUM



O fẹrẹ jẹ pe ni ẹsẹkẹsẹ na ti o ba ti lo "Mentholatum" ni otutu ti nlọ. Fi si iho imu Fi pa ọna-ọfun ti aiya, Bi o ba ti bẹrẹ si fa orun itura "Mentholatum" simu, ni gbogbo idọti agbari ati ti imu a ti bẹrẹ si ijade a si fun aiya ni alafia a ti tuo maa mi daradara Tete lọ ra idẹ tabi agolo "Mentholatum" kan loni. Fi pa aiya ki o si ti i bọ imu.

Bere fun Mentholatum gan an. Eyiti o jẹ pe awọn Mentholatum Co. Ltd., (Est. 1889) Slough, England nikan ni nwọn nṣe e.





ABIYAMỌ BTI RẸ MELO

Abiku ọmọ nda ọ l'amu bi ?
Awọn arun wọnyi ha nyọ ọmọ rẹ lẹnu bi ?

AIPERI
ỌRẸRẸ
INU-IWỌ
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJẸDI

ati orisirisi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'ẹnu ni igba EHIN HIHU. Lọ ra 'YARO' awọ igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde l'ẹnu.

"YARO" ko pe meji ni gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o ri i pe oruko 'YARO' ni o wa lara igo na ki a ma ba ta adamodi egbogi miran fun.


## ỌDUN ILEYA KẸMẸMẸ

AKROSO LẸBA AGỌNA SWEDRU G C—Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu ti o kọja yi ni Ẹgbẹ Ilupeju jo ijo Ọdun Ileya. Ni owurọ ọjọ na ni ẹsẹ gbogbo ẹgbẹ na ti pe si Ile Giwa wọn Ọgbẹni Salami Ajao si fi jijẹ ati mimu tẹ nwọn lọrun.

Lẹhin na ni nwọn jo lọ si ile Ọgbẹni S A Dayiojẹ ẹniti iṣe akọwe ẹgbẹ na ti o si ṣẹṣẹ de lati ilu miran ni ibiti o si lọ ṣiṣẹ. Ọgbẹni S A Dayiojẹ se apọnle wọn, o si fun wọn ni ṣile mejilelogoji (42/-) ati agolo siga kan.

Lẹhin na ni nwọn tun jo pada si ọdọ Giwa wọn, anọwo bi ẹlẹda ọkọ Muni, o si jo bi kokoro, o si fun wọn ni pọnun marun ṣile marun (£5:5s). Nwọn si jo lọ si ile Ọba Yoruba ẹnit o fi tayọtayọ se ọpọlọpọ inawo fun wọn Iya-Afin Madina, awọn Ọgbẹni S Adeyẹmi, B A Akanji, Yesufu Pọju, R Adeọṣun, D Ja-Oluọkun ati J M Iyadunni Sunmonu se gudugudu meje fun iyọrisi daada ti ọjọ na. Ki Oluwa fi ọpọlọpọ ọdun se oju wa ni alafia pelu owo o, amin.

## A BA ỌLỌMỌ YỌ

SAMREABOI—G. C.—A dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ti omọbinrin rubutu kan ti o fi ta Ọgbẹni S. A. Oguntọla ati Iyafin rẹ Alice Abẹni Oguntọla lọrẹ ni ọjọ Riru ti iṣe ọjọ kerin oṣu keje ọdun yi

Nigbati odi ni ọjọ kẹjọ ti iṣe ọjọ isọmọ loruko gẹgẹ bi aṣa awọn Onigbagbọ, ẹsẹ awọn Ijọ Onitẹbomi ti pe ṣọṣọ ni nkan bi agogo mẹfa owurọ. Aṣiwaju isin na ni Michael Faṣanu.

Orukọ ti a fun ọmọ na ni Helena Adebọoyin Oguntọla. Baba ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ Olukuluku awọn ti o wa sibẹ lọrun.

A ki awọn alase ati alabaṣe ọjọ na bi Iya-afin Susanna Kẹhinde, Alice Alari ati ọpọlọpọ awọn obinrin. Ki Oluwa ki o da ọmọ na si, ki o si pin ire kari olukuluku wa o Amin.

E MÁA KA IWE Irohin Yoruba NIGBAGBOGBO

